***Àfojúsùn***

*Àfojúsùn Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Toledo ni láti pèsè àwọn akẹ́kọ̀ọ́jáde tí ó lè bá àwọn akẹgbẹ́ wọn fi iga gbága tí wọ́n sì ṣetán fún ilé-ẹ̀kọ́ gíga àti iṣẹ́ àṣelà nípasẹ̀ ètò ẹ̀kọ́ tí ó jinlẹ̀ jákèjádò gbogbo ipele greedì nípa ṣíṣe àmúlò àwọn Òdíwọ̀n Ìkẹ́kọ̀ọ́ Tuntun ti Ohio pẹ̀lú ìjólóotọ́.*

***Ohun Tí A Ní Lọ́kàn***

*Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Toledo ndù láti jẹ́ aṣáájú agbègbè tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́jáde rẹ̀ ṣetán fún ilé-ẹ̀kọ́ gíga àti iṣẹ́ àṣelà.*

## ÌLÀNÀ AṢỌ WÍWỌ̀ ILÉ-ÌWÉ ALÁKỌ̀Ọ́BẸ̀RẸ̀

****A yọ àwọn ilé-ìwé Alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ yìí kúrò nínú ìlànà aṣọ wíwọ̀ yìí: Ella P. Stewart Academy for Girls, Grove Patterson Academy, Martin Luther King Jr. Academy for Boys, Old West End Academy, Escuela SMART Academy, <u>Chase STEMM Academy, Hawkins STEMM Academy, Marshall STEMM Academy pẹ̀lú McKinley STEMM Academy.</u> Àwọn ilé-ìwé yìí ní ìlànà aṣọ wíwọ̀ tí ó dìídì wà fún ilé tí wọ́n wà. Jọ̀wọ́ kàn sí ọ̀gá ilé-ìwé/ilé-ìwé fún àsọyé. ****

Àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Toledo ti yan àwọn ìlànà aṣọ wíwọ̀ yìí fún gbogbo àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó nlọ sí ọ̀kan nínú àwọn ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ìbílẹ̀ ti Agbègbè yìí. A ní ìrètí pé kí gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ mú ìlànà aṣọ wíwọ̀ yìí ṣe, bẹ̀rẹ̀ láti ọjọ́ àkọ́kọ́ ní ilé-ìwé. Bákan náà, ìrínisí akẹ́kọ̀ọ́ náà jẹ́ ojúṣe àwọn òbí àtí akẹ́kọ̀ọ́.

Èrèdí ìlànà aṣọ wíwọ̀ àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Toledo ni:

- Láti fi ààyè gba ààbò ilé-ìwé
- Láti ṣe àtìlẹ́yìn fún àyíká ìkẹ́kọ̀ọ́
- Láti gbé ìwà rere láruge
- Láti yààgò fún àwọn ìṣòro ìbániwi
- Láti pèsè akẹ́kọ̀ọ́ fún ìgbé-ayé ti iṣẹ́

Àwọn nnkan yìí **<u>KÒ</u>** yẹ:

1. Aṣọ/ìwà tí ó nṣe àfihàn tàbí ṣe ìgbélárugẹ oògùn olóró, ògógóró, tabà pẹ̀lú/tàbí ìbálòpọ̀ tí a sì lè kà sí èyí tí ó nfa ìbínú tàbí tí ó nyẹpẹrẹ àwọn ẹlòmíràn; ó ní àmì ìkórìra tàbí ìmúnisìn; ó ntọ́ka sí jíjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ àwọn oníjàngbọ̀n tàbí tí ó nfa ewu fún ọlọ́dọnni kan tàbí àwọn ènìyàn míràn.
2. Aṣọ/ìwà tí ó nṣe ìdènà fún ètò ẹ̀kọ́:
    a. Kò yẹ kí àwọn aṣọ inú hàn síta ní ìgbàkígbà (lára èyí ni àwọ̀tẹ́lẹ̀, àwọn kọ́mú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ)
    b. Àwọn yẹ̀rì tàbí aṣọ pémpé kò gbọ́dọ̀ sá ga ju òkè eékún lọ.
    c. Àwọn aṣọ tí ó fi okùn nìkan kọ́ apá, tí ó fi okùn nìkan kọ́ ọrùn, èyí tí ó fi èjìká àti àyà hàn, tàbí kòlápá ni a kò fi ààyè gbà.
    d. Àárín ọmú méjèèjì kò gbọ́dọ̀ fi ara hàn ní ìgbàkígbà.
    e. Àwọn ihò/yíya lára jiinsì ni a **kò** fi ààyè gbà, <u>àyàfi tí àwọn ihò náà bá **wà ní ìsàlẹ̀** orí ìka nígbà tí apá bá nà tán.</u>
    f. Aṣọ, tí ó fún pínpín ni a kò fi ààyè gbà. Taitì pẹ̀lú lẹginsì ni a fi ààyè gbà tí iwá jú àti ẹ̀yìn bá ní ṣẹẹ̀tì, yẹ̀rì tábí aṣọ gígùn.
3. Aṣọ/ìwà tí ó dàbí pé **<u>ó léwu</u>** fún yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ tàbí àyíká ilé-ìwé, tìtí dórí ṣùgbọ́n tí kò pin sí àwọn ate/ẹ̀wù/àwọ̀lékè/ìbọ̀wọ́, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ
4. Aṣọ/ìwà tí kò máa ṣe àfihàn ìwà imọ́tọ́tó ara ẹni tí ó dára hàn.

5. Àwọn aṣọ tí a nwọ̀ sókè àti ìsàlẹ̀ tí kò pa lé ara wọn nígbà tí a bá dúró tàbí jókòó (ìyẹn ni pé kò sí aṣọ tí ó fi ikùn, ìdodo, bẹ̀bẹ̀rẹ́ ìdí hàn).

6. Àwọn ṣòkòtò bẹ̀mbẹ̀, títí dórí èyí tí a fi wuulù tàbí òwú tàbí irun ẹranko ṣe.
   Àwọn àfikún ìlànà:

A. Àwọn aṣọ òtútù tí ó ní ìbòrí ni a fi ààyè gbà ní wọ̀n bí a ò ti wọ àwọn ìbòrí tàbí kò máa bo orí.

B. Bàtà gbọ́dọ̀ jẹ́ wíwọ̀ ní gbogbo ìgbà. Fún àwọn èrò ti ààbò, gbogbo bátà gbọ́dọ̀ wà ní síso/wíwọ̀/dídè mọ́ ẹsẹ̀ pẹ̀lú hiilì tí kò ga ju inṣì méjì lọ.

C. Àwọn bàtà pẹnkẹlẹ, àwọn bàtà àtẹsẹ̀bọ̀ pẹ̀lú àwọn bàtà sketín tí ó ṣe é fà padà, àwọn kliitì, tàbí bàtà tí ó ní àtẹ́lẹsẹ̀, tí ó rọ̀ tí ó ṣe é yí (oní rọbà, bàtà etíkun, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) ni a kò fi ààyè gbà. <u>A fi ààyè gba krọọks nìkan tí ó bá jẹ́ pé okùn wà ní ẹsẹ̀ rẹ̀ láti di ẹsẹ̀ mú.</u>

D. A kò fi ààyè gba àwọn bàtà tí ó nfi àtẹ́lẹsẹ̀ tàbí àwọn ọmọ ìka ẹsẹ̀ hàn ní àwọn agbègbè ilé ìtajà tàbí ní àwọn yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ sayẹnsì nígbà tí a bá nlo àwọn kẹmikà.

E. A kò níí fi ààyè gba àwọn ate, ìwérùn, aṣọ tí a fi ngba òògùn, ìwérun, ìbọ̀wọ́, tàbí awò ojú àyàfi nítorí àwọn èrèdí ìlera.

F. Kò sí gèlè tàbí ìwérí àyàfi tí ó bá jẹ́ ti ẹ̀sìn tàbí tí àwọn òṣìṣẹ́ ilé-ìwé fi ọwọ́ síi.

   - Àwọn ìlànà yíí ni a ó tẹ̀lé ní gbogbo ọjọ́ nígbà tí ilé-ìwé bá wà ní ẹnu iṣẹ́ àti fún àwọn ayẹyẹ tí ilé-ìwé ṣe agbátẹrù rẹ̀ níbi tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti nkó ipa ribiribi pẹ̀lú/tàbí tí wọ́n nṣojú àwọn Ilé-ìwé Ìjọba ti Toledo.
   - Ìgbìmọ̀ ìṣàkóso ilé-ìwé yóò pinnu bóyá ìwọṣọ àti ìwà akẹ́kọ̀ọ́ bá ojú mu, ní híhu ìwà nípa àwọn ohun tí ó dára jùlọ ti fífi ìdí múlẹ̀ àti ìmúdúró àyíká ìkẹ́kọ̀ọ́ tí kò léwu tí ó sì múná dóko fún ànfààní ilé-ìwé náà.

G. Gbogbo akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ tẹ̀ l é àwọn ìlànà àti ìgbésẹ̀ tí a là kalẹ̀ nípa wíwọ ìbòjú láti ìtànkálẹ̀ COVID-19.

**Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí kò bá tẹ̀lé ìlànà aṣọ wíwọ̀ náà wà lábẹ́ ìgbésẹ̀ ìbániwí oní ṣísẹ̀-n[tẹ̀lé.**